# ÀGBÉYẸ̀WÒ ÌJẸYỌ ATỌ́KA ÌYÍSÓDÌ NÍNÚ ORÚKỌ ÀBÍKÚ

**Ọlaide AKINWANDE**
University of Lagos

**DOI : https://doi.org/10.5281/zenodo.20757581**

**Àṣamọ̀**
Káríayé ni ìyísódì jẹ́ nínú èdè ọmọnìyàn. Kì í ṣe ohun tuntun pé ìyísódì máa ń jẹ yọ nínú ẹyọ ọ̀rọ̀ Yorùbá bíi ***àbîìkọ́***, ***àkọ́ọ̀gbà***, ***àwîìgbọ́***, ***àfọ̀ọ̀gbà***, abbl yàtọ̀ sí nínú gbólóhùn. Atọ́ka ìyísódì yìí náà ni ó tún ń jẹ yọ nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá kan, irú èyí tí ẹnikẹ́ni kò tí ì ṣiṣẹ́ lórí rẹ̀ rí. Àpilẹ̀kọ yìí jíròrò lórí ìyísódì tó máa ń jẹ yọ nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá kan. Ètò girámà oníwọ̀nba-èròja (minimalist program) ti Chomsky (1995, 1998, 2002) ni iṣẹ́ yìí gùnlé fún ìtupalẹ̀ ẹ̀hun ìyísódì nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá náà. Àpilẹ̀kọ yìí ṣàlàyé pé ọ̀nà mẹ́ta ni ìyísódì ń gbà jẹ yọ nínú àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì bí a bá ṣe ìtúpalẹ̀ ìhun àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá bẹ́ẹ̀: orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòólà ìṣe, orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn, àti orúkọ àbíkú oníyìsódì odindi gbólóhùn. Iṣẹ́ yìí tún jíròrò lórí orúkọ àbíkú oníyìsódì kan tí wúnrẹ̀n ìyísódì wọn kò fojú hàn nínú ìhun òke àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì bẹ́ẹ̀ àyàfi bí a bá tanná wo ìhun ìpìlẹ̀ (nínú ìtúpalẹ̀ àti àlàyé ajẹmọ́-sẹ̀mánṭíìkì) wọn. Lẹ́yìn náà ni àpilẹ̀kọ yìí kádìí ọ̀rọ̀ nílẹ̀ nípa ṣíṣe àfihàn àgbéjáde ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì Yorùbá náà nínú èyí tí wúnrẹ̀n ìyísódì (IY) ti yan àpólà àsìkò (APAS) tàbí àpólà ìṣe (APIṢ) gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbeyọ ìhun rẹ̀.

**Kókó ọ̀rọ̀:** Àpólà ìṣe, Awẹ́-gbólóhùn, Gbólóhùn, Ìyísódì, Orúkọ Àbíkú

## 1. Ìfáàrà

Ìsọ̀rí kan pàtàkì ni orúkọ àbíkú jẹ́ nínú àwọn orúkọ Yorùbá (Adeoye 1969, Adebiyi 2005, Oyebanjọ, ati ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ 2009, Ogunwale 2016, abbl). Ogunwale (2016:142) ṣe àpèjuwe orúkọ àbíkú báyìí:

> Àbíkú names are the names given to the children
> that are believed to be members of a group of spirit-nymphs in Yorùbá anthropology. These children, however, take on mortal existence that is why they are born like normal human beings at first instance but only to die at the time specified by the celestial group members which is usually shortly after and return to the group.
> (Orúkọ àbíkú ni orúkọ tí a fún àwọn ọmọ ẹlẹ́gbẹ́ nínú ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ẹ̀dá ènìyàn. Àwọn ọmọ wọ̀nyí máa ń gbé àgọ́ ènìyàn wọ̀,ìdí sì nìyí tí wọ́n kọ́kọ́ máa ń bí wọn gẹ́gẹ́ bí ọmọ gidi ṣùgbọ́n tí wọ́n máa ń padà kú ní àsìkò tí àwọn ẹgbẹ́ ọ̀run wọn dá fún wọn tí kì í pẹ́ jù lẹ́yìn tí a bí wọn, wọ́n á sì padà sínú ẹgbẹ́ wọn).

Nígbà mìíràn, tí àwọn òbí bá dá ọgbọ́n sí irú àwọn ọmọ báyìí, tí wọ́n sì gbàdúrà sí Ẹlẹ́dàá, àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ lè má kú mọ́ gẹ́gẹ́ bí ìṣe wọn. Ẹ̀wẹ̀, ohun kan tó hànde nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá ni ìyísódì. Lóòótọ́, kì í ṣe gbogbo orúkọ àbíkú Yorùbá ni ó ní ìyísódì yìí, àmọ́ àwọn tó ní ìyísódì ni àpilẹ̀kọ yìí dojú kọ. Kókó tó gbajúgbajà ni ìyísódì jẹ́ nínú gírámà kárí-ayé, èyí tí kò yọ èdè Yorùbá sílẹ̀. Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ gírámà Yorùbá ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ tó mọ́yán lórí ìyísódì[1] yálà nínú Yorùbá

[1] Ajiboye (2024) ṣe àpèjuwe ìyísódì gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ọ̀gangan afọ̀-afìmọ̀lára-hàn tí wúnrẹ̀n ìyísódì aláìlera ti máa ń jẹ yọ.

àjùmọ̀lò tàbí àwọn ẹ̀ka-èdè rẹ̀ (Bamgboṣe 1967, 1990; Ogunbọwale 1970, Banjọ 1974, Awobuluyi 1978, Oke 1982, Adewọle 1999, Ilọri & Oyebade 2012, Fabunmi 2013, Adeoye 2018, Adebayọ 2021, Ajiboye[2] 2024), abbl. Gbogbo àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni wọ́n ti jírórò lórí ìyísódì lọ́nà kan tàbí òmíràn nínú iṣẹ́ wọn ṣùgbọ́n kò sí èyí tó ṣiṣẹ́ lórí ìyísódì nínú orúkọ àbíkú Yorùbá nínú wọn. Ẹ̀wẹ̀, wúnrẹ̀n ìyísódì ni àwọn onímọ̀ ti ṣàpèjuwe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí wúnrẹ̀n onítúmọ̀ gírámà (Pollock 1989, Haegeman 1991, 1995, Kayne 1994, Chomsky 1995, Baker 2003, abbl). Ilọri (2010:153) rí wúnrẹ̀n ìyísódì gẹ́gẹ́ bíi àfòmọ́ (inflection). Àwọn wúnrẹ̀n míìràn tí a tún lè rí ní ipò àfòmọ́ ni atọ́ka àsìkò, ibá-ìṣẹ̀lẹ̀, múùdù, abbl. Àwọn wúnrẹ̀n tí àwọn onímọ̀ gírámà Yorùbá gbà pé ó jẹ́ wúnrẹ̀n ìyísódì nínú èdè Yorùbá ni ***kò/ò, kì, kọ́,*** ati ***má/máà.*** Abala mẹ́fa ni iṣẹ́ yìí pín sí. Tíọ́rì àmúlò ni abala kejì sọ̀rọ̀ lé lórí. Ìhun ìyísódì àwọn orúkọ àbíkú ni abala kẹta jírórò lé lórí. Abala kẹrin ṣàlàyé lórí orúkọ àbíkú oníyìsódì afarasin. Àgbéjáde ìhun orúkọ àbíkú oníyìsódì ni abala karùn-ún ṣàtupalẹ̀ rẹ̀, nígbà tí abala tí ó parí jẹ́ ìkádìí.

## 2. Tíọ́rì Àmúlò

Ètò gírámà oníwọ̀nba-èròja (minimalist program) ti Chomsky (1995, 1998, 2002) tí a ṣe àfàyọ ẹ̀dà Yorùbá rẹ̀ láti inú Ilọri (2015:127-130) pẹ̀lú àtunṣe díẹ̀ ni pépà yìí ṣe àmúlò fún àlàyé àti itúpalẹ̀. Gírámà náà jẹ́ ẹ̀yà tíọ́rì onídàrọ ti Noam Chomsky àti àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ ń ṣàmúlò láti ọdún 1957 títí di òní. Gírámà oníwọ̀nba-èròjà yàtọ̀ díẹ̀ sí gbogbo àwọn ẹ̀yà tíọ́rì onídàrọ tó ti wà ṣáájú rẹ̀ bíi tíọ́rì afòtéwogàba (government-binding theory) lọ́nà tó lápẹẹrẹ. Torí pé èròǹgbà Chomsky ni láti fi hàn pé irin-iṣẹ́/èròjà àti àwọn òfin tí gírámà kárí-ayé (Universal Grammar) àti gírámà èdè kọ̀ọ̀kan (Internal Language) ń múlò fún ìṣẹ̀dá àpólà àtí gbólóhùn kò ju pérete lọ, èyí tó mú kó rọrùn fún àwọn ọmọdé láti kọ́ èdè, pàápàá èdè abínibí wọn, níwọ̀nba àsìkò pérete, ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn òfin àti òté gírámà oríṣiríṣi tó wà nínú àwọn tíọ́rì onídàrọ ti tẹ̀lẹ̀ ló yọ kúrò pátápátá nínú gírámà oníwọ̀nba-èròjà, ó sì ṣe àtúnṣe sí àwọn kan.

Díẹ̀ nínú àwọn òfin àti òté tó yọ kúrò ni: gbé-álífà/α (move-alfa/α); tíọ́rì àmì (trace theory) èyí tó gbà pé wúnrẹ̀n tí a bá gbé nínú ìhun gírámà máa ń fi àmì sílẹ̀ lọ́gangan tí a bá ti gbé e; tíọ́ri kéèsì (case theory); abbl. Lára àwọn tó ṣe àtúnṣe sí ni tíọ́rì ààtò wúnrẹ̀n nínú ìhun, ìyẹn tíọ́rì ààtò onípele (x-bar theory) àti ìfọ́síwẹ́wẹ́ àpólà aṣèrànwọ́ pẹ̀lú àpólà amúpé láti jẹ́ kí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ gírámà tó wà nínú àwọn àpólà yẹn dá dúró gẹ́gẹ́ bí orí nínú ìhun àpólà wọn. Ìyẹn ló bí àwọn àpólà bí àpólà ìyísódì (APIY) tí a mú lò nínú iṣẹ́ yìí. Tíọ́rì kan tí kò yí padà nínú ètò gírámà oníwọ̀nba-èròjà ni ti ẹ̀hun akópa (argument structures) èyí tó jẹ mọ́ yíyan àwọn iṣẹ́ akópa (theta roles/assignment) nínú ìhun gbólóhùn. A ṣàmúlò abala yìí nìnu àlàyé wa.

### 2.1. Irin-Iṣẹ́ Gírámà Oníwọ̀nba-Èròjà

Irin-iṣẹ́ méjì pàtàkì ni gírámà oníwọ̀nba-èròjà ń ṣàmúlò. Ìkínní ni àká-ọ̀rọ̀ tí tíọ́rì náà gbà pé ó wà nínú ọpọlọ elédè níbi tí a ṣe gbogbo ọ̀rọ̀ inú èdè kọ̀ọ̀kan lọ́jọ̀ sí. Ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan nínú àká yìí nìgbàgbọ́ wà pé ó ní àbùdá kárí-ayé mẹ́ta-mẹ́ta: [Sẹ̀má, Síńtá, Fònẹ̀][3]. Ìkejì ni ìhunpọ̀ (merge) tó jẹ́ ìgbésẹ̀ ìṣirò kan tí èdè ọmọnìyàn ń mú lò láti ṣẹ̀dá ìhun àpólà/gbólóhùn nípa híhun àwọn ọ̀rọ̀ tí a ti ṣà láti inú àká-ọ̀rọ̀ pọ̀ mọ́ra wọn ní méjì-méjì. Nítorí pé ìlànà ẹ̀hun oníbejì ni ìhunpọ̀ yìí ń tẹ̀lé, gírámà oníwọ̀nba-èròjà kò fàyè gba ìhun ẹlẹ́ka mẹ́ta tàbí èyí tó jù bẹ́ẹ̀ lọ. Kódà kò fàyè gba ìhun ẹlẹ́ka kan èyí tó máa jẹ yọ nínú tíọ́rì afòtéwogàba. Iṣẹ́ ìhunpọ̀ yìí lágbára débi pé ó lè hun ọ̀rọ̀ pọ̀ mọ́ odindi

[2] Wo Ajiboye (2024:229-231) fún àpẹẹrẹ àwọn wúnrẹ̀n ìyísódì aláìlera báyìí.

[3] Ìgékúrú sẹ̀mańtíìkì, síńtáàsì, àti fònẹ́tíìkì nìwọ̀nyí.

àpólà/gbólóhùn tí a ti ṣẹ̀dá tẹ́lẹ̀, iye ìgbà tí ìgbésẹ̀ ọ̀hún sì lè wáyé kò ní gbèdéke. Ìyẹn ni pé a lè mú un lò níye ìgbà tí a bá nílò rẹ̀ nínú ìṣẹ̀dá ìhun kan péré.
Fún àpẹẹrẹ, a lè hun α àti β pọ̀ kó fún wa ní {α{α, β}} tí α bá jẹ́ orí tàbí {β{α, β}} tí β bá jẹ́ orí. Bákan náà ni a lè hun {α{α, β}} mọ́ wúnrẹ̀n mìíràn, b.a. γ, kí àyọrísí rẹ̀ sì fún wa ní {γ {γ}{α{α, β}}}. Oríṣi ìhunpọ̀ méjì ló wà: ìkínní ni ìhunpọ̀ àti-ìta (external merge). Ìyẹn ní í ṣe pẹ̀lú ṣíṣa ọ̀rọ̀ tààrà láti inú àká-ọ̀rọ̀ fún ìhunpọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n mìíràn gẹ́gẹ́ bó ṣe hàn nínú àpẹẹrẹ tí a ti tọ́ka sí ṣaájú; ìkejì ni ìhunpọ̀ àti-inú (internal merge) èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú ìgbésẹ̀ híhun ọ̀rọ̀/wúnrẹ̀n tó ti wà nínú ìhun tí a ti ṣẹ̀dá tẹ́lẹ̀ mọ́ abala mìíràn nínú ìhun yẹn kan náà. Èyí fara pẹ́ ìgbéfò ṣùgbọ́n ohun tó yà á sọ́tọ̀ sí ìgbéfò ni pé kò sí ọ̀rọ̀ pé wúnrẹ̀n tí a gbé fi àmì sílẹ̀ níbi tí a bá ti gbé e àtipé ète láti ṣàyẹ̀wò àbùdá ọ̀rọ̀ tó jẹ́ orí láti ipò wúnrẹ̀n asọdọ̀tọ̀ (specifier) rẹ̀ ló máa ń fa irúfẹ́ ìhunpọ̀ yìí.

## 2.2. Ààtò Girámà Oníwọ̀nba-Èròjà

Inú àká-ọ̀rọ̀ ni gbogbo ìṣẹ̀dá ìhun síńtáàsì ti ń bẹ̀rẹ̀ nínú gírámà oníwọ̀nba-èrójà. Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ ni ṣíṣa àwọn ọ̀rọ̀ tí a fẹ́ mú lò sọ́tọ̀ láti inú àká-ọ̀rọ̀ (lexicon) lọ sínú àpò àṣàyàn ọ̀rọ̀ (numeration). A óò rántí pé gbogbo ọ̀rọ̀ tó wà nínú àká-ọ̀rọ̀ yìí ló ní àbùdá kárí-ayé mẹ́ta-mẹ́ta: [Sẹ̀má, Síńtá, Fònẹ́]. Àbùdá ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ló máa ń tẹ̀lé wọn lọ sínú àpò àṣàyàn ọ̀rọ̀ torí pé bí ìgbín bá fà lọ̀rọ̀ ọ̀hún, dandan ni kí ìkarahun rẹ̀ tẹ̀lé e.
Láti inú àpò àṣàyàn ọ̀rọ̀ ni ìhunpọ̀ yóò ti bẹ̀rẹ̀ sí í wáyé. Àyọrísí ìgbésẹ̀ ìhunpọ̀ ni ìṣẹ̀dá ìhun síńtáàsì èyí tá a ní àǹfààní láti gbé jáde lọ́nà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀: *Àgbéyọ A-pẹṣẹ́-fún-ẹ̀yà-ara* (Sensory-Motor Interface) àti *Àgbéyọ Èrò* (Conceptual-Intentional Interface). Àwòràn bí ààtò yìí ṣe ń ṣiṣẹ́ la fi hàn nínú àtẹ 1 ní ìsàlẹ̀ yìí tí a mú láti inú Ilọri (2015:130).




Ààtò àti àwọn irinṣẹ́ gírámà oníwọ̀nba-èròjà tí a ṣàlàyé lókè yìí ni a óò mú lò nínú ìtupalẹ̀ ìhun àti àgbéyọ àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì nínú iṣẹ́ yìí.

# 3. Ìhun Ìyísódì Orúkọ Àbíkú Yorùbá

Nínú iṣẹ́ yìí, àwọn àkójọ-ẹ̀rí-fáyẹ̀wò fi hàn pé ọ̀nà mẹ́ta ni ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì Yorùbá pín sí. A óò ṣe àlàyé wọn ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.

## 3.1. Orúkọ Àbíkú Oníyìsódì Alápòólà Ìṣe

Àwọn àkòjọ-ẹ̀rí-fáyẹ̀wò fi hàn pé àwọn orúkọ àbíkú kan wà tí wọ́n ní ìyísódì tó jẹ́ pé nínú àpólà ìṣe (APIṢ) pọ́ńńbélé ni wọ́n ti ń jẹ yọ. Àwọn atọ́ka ìyísódì tó sáábà máa ń ṣe atọ́nà irú orúkọ àbíkú báyìí ni ***má*** àti ***kò*** gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (2).

| | | | |
|---|---|---|---|
| 2a. | Málọmọ́ | - | (Ọmọ) má lọ mọ́ |
| b. | Mákùú | - | (Ọmọ) má kù ú mọ́ |
| d. | Mákòó | - | (Ọmọ) má kó mi ní ẹrù lọ |
| e. | Mámòórá | - | (Ọmọ) má mú owó rá |
| ẹ. | Máyungbó | - | (Ọmọ) má tún lọ inú igbó mọ́ |
| f. | Máyungbẹ̀ẹ́ | - | (Ọmọ) má tún lọ inú ìgbẹ́ mọ́ |
| g. | Kòkúmọ́ | - | (Ọmọ) kò kú mọ́ |
| gb. | Kòtóyẹ́ | - | (Ọmọ) kò tó yẹ́ sí |
| h. | Kòsọ́kọ́ | - | Kò sí ọkọ́ |

Ẹ̀dà méjì ni àwọn orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì alápòólà ìṣe nínú àwọn orúkọ àbíkú òkè wọ̀nyí ni. Àkọ́kọ́ ni àwọn tó ní ẹ̀dà ***má*** ní ìbẹ̀rẹ̀ ìhun wọn (2a-f). Ẹ̀dà kejì ni àwọn tó ní ***kò*** ní ìbẹ̀rẹ̀ ìhun wọn (2g-h). Bí a bá wo àwọn orúkọ àbíkú wọ̀nyí dáradára, a ó ri wí pé APIṢ pọ́nńbélé ni wọ́n. Ìyẹn ni pé atọ́ka ìyísọ́dì pẹ̀lú APIṢ ni wọ́n ń ṣe. Gẹ́gẹ́ bí gbogbo wa ṣe mọ̀, ara APIṢ ni wúnrẹ̀n ìyísọ́dì wà nínú èdè ọmọnìyàn. Nínú àpẹẹrẹ (2) lókè, àwọn kan jẹ mọ́ atọ́ka ìyísọ́dì pẹ̀lú àtòpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe (IṢ) àsínpọ̀ (2a, g, gb). Àwọn orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì alápòólà ìṣe mìíràn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (2) yìí tún ní ìyísọ́dì pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀ rẹ̀ nínú ìhun wọn (2b-f). (2h) nìkan ló dábí pé ìhun rẹ̀ yàtọ̀ gédéńgbé níbi tí a ti rí atọ́ka ìyísọ́dì pẹ̀lú atọ́kùn àti àbọ̀ rẹ̀. Wọ̀fún tàbí asọdọ̀tọ̀ ni ***ọmọ*** tí a fi sínú àkámọ́ jẹ́ ní (2). Àmọ̀ bí a bá fi ojú ẹ̀hun akópa (argument structures) wo àpẹẹrẹ (2), a lè sọ pé akópa kan péré ni IṢ (2a, g, gb àti h) yàn fún isẹ́ ajẹmọ́-tumọ̀ nínú orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì alápòólà ìṣe rẹ̀, èyí sì ni ***ọmọ*** tó jẹ́ olùṣe tó wà nínú àkámọ́ (2a, g àti gb) àti ***ọkọ́*** tí ó jẹ́ afaragbàṣẹ̀lẹ̀ ní (2h). Akópa méjì ni IṢ (2b àti e) yàn, àwọn sì ni ***ọmọ*** tí ó jẹ́ olùṣe àti ***owó*** tí ó jẹ́ afaragbàṣẹ̀lẹ̀. IṢ (2d, ẹ àti f) yan akópa mẹ́ta fún isẹ́ ajẹmọ́-tumọ̀ nínú orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì alápòólà ìṣe wọn. Àwọn akópa (2d) ni ***ọmọ*** (olùṣe), ***mi*** (afaragbàṣẹ̀lẹ̀), àti ***ẹrù*** (àbọ̀ atọ́kùn), nígbà tí akópa (2ẹ àti f) jẹ́ ***ọmọ*** (olùṣe) àti ***inú igbó/inú ìgbẹ́*** (afaragbàṣẹ̀lẹ̀). Èyí já sí wí pé iṣẹ́ afaragbàṣẹ̀lẹ̀ ni akópa kejì àti ìkẹta ṣe ní (2ẹ àti f).

### 3.2. Orúkọ Àbíkú Oníyìsọ́dì Aláwẹ́-gbólóhùn

Àwọn orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì tó wà ní ìsọ̀rí yìí ni àwọn tó ń jẹ yọ nínú awẹ́-gbólóhùn kání. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni atọ́ka awẹ́-gbólóhùn aṣàpọ́nlé ***bí*** tí ó bẹ̀rẹ̀ àwọn orúkọ àbíkú bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (3).

| | | | |
|---|---|---|---|
| 3a. | Bíòbákú | - | Bí kò bá kú |
| b. | Béyìíòkú | - | Bí èyí ò kú |

Ọ̀nà méjì ni àwọn orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì aláwẹ́-gbólóhùn wọ̀nyí ń gbà ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àpẹẹrẹ (3) lókè. Ìkíní ni èyí tí atọ́ka awẹ́-gbólóhùn bẹ̀rẹ̀ rẹ̀, tí wúnrẹ̀n ìyísọ́dì sì jẹ yọ lẹ́yìn atọ́ka awẹ́-gbólóhùn náà tààrà (3a). Ìkejì ni èyí tí ó ní atọ́ka awẹ́-gbólóhùn ní ìbẹ̀rẹ̀ àmọ́ tí àpólà orúkọ (APOR) kan la atọ́ka awẹ́-gbólóhùn àti wúnrẹ̀n ìyísọ́dì láàrin (3b). Ìyẹn ni pé wúnrẹ̀n ìyísọ́dì kò tẹ̀lé atọ́ka awẹ́-gbólóhùn náà tààrà. Bí a bá fojú ẹ̀hun akópa wò ó, a lè sọ pé (3a) kò ní akópa kankan, àmọ́ IṢ inú (3b) yan akópa kan tó fojú hàn, ìyẹn ***èyí*** tí ó jẹ́ olùṣe. Ẹ̀wẹ̀, ìhun orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì aláwẹ́-gbólóhùn ní (3a) àti (3b) gba àlàyé. Ohun àkọ́kọ́ tí a wòye rẹ̀ ni pé irú àwọn orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì aláwẹ́-gbólóhùn bíi (3a) àti (3b) jẹ́ aláwẹ́ méjì. Abala awẹ́ àkọ́kọ́ ni Yorùbá fi ń fún ọmọ ní orúkọ àbíkú tó hànde, nígbà tí abala awẹ́ kejì jẹ́ mọ̀-ọ́n-nú fún òbí ọmọ àti àwùjọ. Bí a bá bojú wo ìyàtọ̀ ìhun (3a) àti (3b) níbi tí (3a) kò ti ní APOR nínú, a wòye pé nínú irú orúkọ àbíkú oníyìsọ́dì aláwẹ́-gbólóhùn báyìí, APOR yẹn wà níbẹ̀, ó kàn farasin ni. APOR náà ni ***èyí,*** tí ó lè jẹ yọ ṣáájú wúnrẹ̀n ìyísọ́dì ***kò*** níbẹ̀. Àlàyé tí a rí ṣe sí èyí jẹ mọ́ ète kan tí gírámà kárí-ayé máa ń ṣàmúlò nínú síńtáàsì níbi tí a ti ń gbé odindi ọ̀rọ̀ mì (ìgékúrú (Vries 1992, Ajiboye 2016, Taiwo 2016, abbl)) bí a bá ń ṣe afọ̀ geere. Bí a bá tún ṣàmúlò ẹ̀hun-aláàtò fọ́nrán-ìhun (constituent

structure (Erteschick-Shir, 2007:69)), a tún lè gbé odindi fọ́nrán-ìhun kan mì. Èyí já sí wí pé ṣe ni àwùjọ Yorùbá mọ̀-ọ́n-mọ̀ gbé APOR ***èyí*** tí ó wà nínú orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn ní (3a) bẹ́ẹ̀ mì. Ẹ̀wẹ̀, nípa (3b) níbi tí APOR kan ti jẹ yọ láàrin atọ́ka awẹ́-gbólóhùn àti wúnrẹ̀n ìyísódì, a lè sọ pé iṣẹ́ ìtẹnumọ́ ni APOR ***èyí*** (ẹ̀yán atọ́ka aṣàfihàn/olùṣe) tó jẹ yọ nínú orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ń ṣe, ohun tí ó sì ń tẹnumọ́ náà ni ***ọmọ*** (tí àwọn òbí ń rò pé bí kò bá kú, yóò sanjọ́ fún àwọn). Iṣẹ́ ìtẹnumọ́ náà ni APOR ***èyí*** tó fara sin ní (3a) náà ń ṣe pẹ̀lú. Ohun tí èyí ń ṣàfihàn nínú orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn báyìí ni pé orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn lè jẹ́ *alátẹnumọ́ ahànde* (tí APOR rẹ̀ hànde bíi ti (3b)), ó sì lè jẹ́ *alátẹnumọ́ afarasin* (tí APOR rẹ̀ fara sin bíi ti (3a)), gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàfihàn rẹ̀ nínú àwòrán ìsàlẹ̀ yìí ní (4).

4.




Nínú àwòrán (4), orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn ló bí orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn alátẹnumọ́, orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́-gbólóhùn alátẹnumọ́ ló sì pẹ̀ka sí méjì: alátẹnumọ́ ahànde àti alátẹnumọ́ afarasin.

**3.3. Orúkọ Àbíkú Oníyìsódì Odindi Gbólóhùn**

Ọ̀nà mìíràn tí atọ́ka ìyísódì ń gbà jẹ yọ nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá kan ni atọ́ka ìyísódì tó ń wáyé nínú ìsọgbólóhùndorúkọ àbíkú. Lára àwọn orúkọ àbíkú bẹ́ẹ̀ ni ó wà ní (5).

| | | | |
|---|---|---|---|
| 5a. | Adékògbé | - | Adé (k)ò gbé. |
| b. | Ajéìígbé | - | Ajé (k)ì í gbé. |
| d | Adéìígbé | - | Adé (k)ì í gbé. |
| e. | Aòmọnurẹ̀ | - | A kò mọ inú ọmọ yìí. |
| ẹ. | Ikúmápàyí | - | Ikú má pa èyí. |

Ohun àkọ́kọ́ tó jẹ́ ọ̀títọ́ ni pé, àwọn orúkọ tó wà ní (5) jẹ́ orúkọ àbíkú Yorùbá. Bí a bá gbà pé àwọn orúkọ tó wà ní (5) jẹ́ orúkọ àbíkú, ní àkọ́kọ́, a ó rí i pé atọ́ka ìyísódì wà nínú wọn àti pé gbólóhùn ni ó para pọ̀ di orúkọ àbíkú wọ̀nyí, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní apá ọ̀tún. Bí a bá tẹ̀lé òfin ààtò ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá tó ṣe àmúlò ***olùwà***, ***ọ̀rọ̀-ìṣe,*** àti ***àbọ̀*** (O-IṢ-A), a ó rí i pé àwọn gbólóhùn tó yírapadà di orúkọ àbíkú oníyìsódì wọ̀nyí tẹ̀lé òfin ààtò ọ̀rọ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìsọ olórúkọ àbíkú oníyìsódì ní (5a-d) kò ní àbọ̀, síbẹ̀, èyí kì í ṣe tuntun torí pé àwọn gbólóhùn kan wà nínú èdè Yorùbá tí ààtò ọ̀rọ̀ inú ìhun wọn kò ní àbọ̀, ṣùgbọ́n tí ìhun wọn jẹ́ olùwà àti ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan. Irú àwọn ìhun báyìí pọ̀ jàǹtìrẹrẹ nínú èdè Yorùbá. Bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí, àwọn ìsọ olórúkọ àbíkú ìyísódì ní (5a-d) ní olùwà, tí wúnrẹ̀n ìyísódì tó ṣe àgbéjáde ìtumọ̀ ìyísódì tí ó wà nínú orúkọ àbíkú ìsọgbólóhùndorúkọ bẹ́ẹ̀ sì jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ààtò ìhun wọn. Àpẹẹrẹ (5e àti ẹ) ní tirẹ̀ ní olùwà, ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀. Ẹ̀dà ***kò/kì*** ni atọ́ka ìyísódì tó jẹ yọ ni (5a-e), nígbà tí (5ẹ) ní ẹ̀dà atọ́ka ìyísódì ***má***. Akópa kan (Adé/Ajé) tí ó jẹ́ olùṣe ni IṢ (5a-d) yàn. IṢ (5e) ní tirẹ̀ ní akópa mẹta, ìyẹn ni ***a*** (olùṣe), ***inú*** àti ***ọmọ*** tí ó jẹ́ afaragbàṣẹ̀lẹ̀. IṢ (5ẹ) yan akópa méjì, ìyẹn ***ikú*** (olùṣe) àti ***èyí*** (afaragbàṣẹ̀lẹ̀).

**4. Orúkọ Àbíkú Oníyìsódì Afarasin**

Àkíyèsí wa tún fi hàn pé àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì mìíràn tún wà nínú èyí tí wúnrẹ̀n ìyísódì kò fojú hàn nínú ìhun òke àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì bẹ́ẹ̀ àyàfi bí a bá tanná wo ìhun ìpìlẹ̀ (nínú ìtúpalẹ̀) àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn ní (6) ní apá ọ̀tun.

6a. Orúkọtán - [Kò] sí orúkọ mìíràn tí a ó sọ ọ́
b. Abíiná - A bí ọmọ yìí ná, a [kò] mọ èyí tí yóò tún ṣe
d. Ẹkúnsúmi - A [ò] tún sọkún nítorí tìrẹ mọ́
e. Èkísàtán/Àkísàtán - [Kò] sí aṣọ èkísà/àkísà tí a ó fi sin ọ́ mọ́

Àwọn orúkọ àbíkú tí ó wà ní apá òsì ni a kà sí ìhun òkè bí a bá fi ojú tíọ́rì onídàrọ (Chomsky, 1957) wò ó. Àwọn orúkọ àbíkú wọ̀nyí kò ní ìrísí atọ́ka ìyísódì kan nínú wọn. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé àyipadà ti wà nínú orúkọ àbíkú náà kí á tó gbé wọn jade. Àwọn ìtúpalẹ̀ tí ó wà ní apá ọ̀tún ni a kà sí ìhun ìpìlẹ̀ tí àatò gírámà rẹ̀ ti ní ìpalára nipa gbígbé àwọn ọ̀rọ̀ kan mì àti pípa àwọn ọ̀rọ̀ kan jẹ, kí á tó wá ní ìhun òkè. Nínú àtúpalẹ̀ (ní ìpele ìtumọ̀[4]) àwọn orúkọ àbíkú báyìí pẹ̀lú àlàyé ajẹmọ́-sẹ̀mańtíìkì[5] ni fọ́nrán ìyísódì ti fojú hàn. Fọ́nrán ìyísódì náà ni a sì yà sọ́tọ̀ (mapping) nínú àkámọ́ onídodo (labelling bracketing) ní (6a-e) yẹn.

**5. Àgbéjáde Àwọn Orúkọ Àbíkú Oníyìsódì Yorùbá**

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣáájú pé tíọ́rì oníwọ̀nba-èròjà (Minimalist Program) ni iṣẹ́ yìí ṣàmúlò láti ṣe àgbéjáde àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì Yorùbá, ọ̀nà mẹ́ta gbòógì ni atótónu wa pín àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì Yorùbá sí. A óò mú orúkọ kan lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan fún ìtúpalẹ̀ àti àgbéjáde ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì náà. Fún àpẹẹrẹ, ***Mákòò*** tí ó jẹ́ orúkọ àbíkú oníyìsódì ni a mú láti ṣe ìtúpalẹ̀ àti àgbéjáde ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòòlà ìṣe. Ìdí tí a fi mú ***Mákòó*** ni pé àwọn atọ́kùn kan jẹ yọ nínú àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòòlà ìṣe kan (1d àti h). Èrò wa ni pé lílo ***Mákòó*** gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n fún àgbéjáde ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòòlà ìṣe báyìí yóò ṣe àkótán pátápátá fún àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòòlà ìṣe yálà èyí tí àkóónú wọn ní atọ́kùn tàbí èyí tí kò ní atọ́kùn. Wàyí ò, àgbéjáde náà lọ báyìí: APOR ***ẹrù****,* tí ó jẹ́ àfikún fún IṢ ***lọ***, èyí tí a ti gbé kúrò ní ipò rẹ̀ lọ sí ipò asọdọ̀tọ̀ APIṢ1 ni IṢ ***lọ*** yàn gẹ́gẹ́ bí àfikún tí ó fún wa ní IṢ' (onípele kan/oníbáà kan). IṢ' onípele kan yìí ni ó sì ṣe àgbéjáde APIṢ1. Lẹ́yìn èyí ni atọ́kùn (AT) ***ní*** yan APIṢ1 gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbéyọ AT' oníbáà kan. AT' oníbáà kan ló ṣe àgbéjáde àpólà atọ́kùn (APAT), tí APAT yìí sì ta mọ́ àsọdọ̀tọ̀ (ASỌD) ***mi*** láti ṣe àgbéyọ pátápátá (maximal projection). Gẹ́rẹ́ bẹ́ẹ̀ ni IṢ ***kó*** yan APAT gẹ́gẹ́ bí àfikún, tí ó sì ṣe àgbéjáde IṢ' onípele kan. IṢ' onípele kan yìí ni ó ṣe àgbéjáde APIṢ2, tí APIṢ2 sì fò mọ́ ASỌD oníkòròfo. Lẹ́yìn èyí ni ìyísódì (IY) ***má*** tí ó jẹ́ orí yan APIṢ2 gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbéyọ IY' oníbáà kan, IY' oníbáà kan sì ṣe àgbéjáde àpólà ìyísódì (APIY), èyí tí ó fún wa ní orúkọ àbíkú oníyìsódì alápòòlà ìṣe. Àwòrán atọ́ka igi irú àgbéjáde báyìí ni a ṣe àfihàn rẹ̀ ní (7).

---

[4] A kò ṣe àgbéjáde ẹ̀hun orúkọ àbíkú oníyìsódì afarasin torí pé nínú àlàyé ajẹmọ́-sẹ̀mańtíìkì ni wúnrẹ̀n ìyísódì wọn ti fojú hàn.

[5]Ogunwale (2016:143-158) ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé ajẹmọ́-sẹ̀mańtíìkì lórí àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá.

7. Mákòó




Ẹ̀wẹ̀, àgbéjáde orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́ gbólóhùn ni ìkejì tí a óò ṣàlàyé báyìí. Àgbéjáde yìí ṣàfihàn rẹ̀ pé APOR ***èyí*** tí a ti kọ́kọ́ gbé kúrò ní ipò rẹ̀ lọ sí ipò ASỌD-APIY1 pẹ̀lú ìgbésẹ̀ méjì ni IṢ ***kú*** yàn gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbéyọ IṢ' onípele kan, IṢ' onípele kan yìí ni ó sì ṣe àgbéjáde APIṢ. IY ***kò*** tí ó jẹ́ orí fún APIY1 yan APIṢ gẹ́gẹ́ bi àfikún láti ṣe àgbéyọ IY' oníbàá kan, IY' oníbàá kan sì ṣe àgbéjáde APIY1. Lẹ́yìn náà ni APIY1 ràn mọ́ ASỌD ***èyí*** fún àgbèjáde pátápátá (maximal projection). Lẹ́yìn èyí ni amúpé ***bí*** yan APIY1 gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbéjáde àpólà amúpé (APAM). Ní ìkórita yìí, a dábàá kí á ní APIY2. Orí APIY2[6] tí ó jẹ́ kòròfo ni ó yan APAM gẹ́gẹ́ bí àfikún láti ṣe àgbéjáde APIY2. Ìdí tí ó fi pọndandan láti ṣe àgbéjáde APIY2 ni pé ìhun àpólà tí a bá ń ṣe àgbéjáde rẹ̀ nínú èdè ọmọnìyàn ní ó máa ń pèkun àgbéjáde pátápátá, nígbà tí ó sì jẹ́ pé ìyísódì ni ìhun orúkọ àbíkú tí à ń ṣe àgbéjáde rẹ̀ ní, èyí di dandan kí àgbéjáde tí ó pèkun jẹ́ APIY. Ìdí nìyí tí a ṣe dábàá APIY2 gẹ́gẹ́ bí àgbéjáde tí ó pèkun, kí ó ba lè ṣàfihàn ìhun orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́ gbólóhùn tí à ń ṣe àgbéjáde rẹ̀.

Bí a kò bá ṣe èyí, a jẹ́ wí pé APAM ni yóò jẹ́ àgbéjáde tí ó pèkun, èyí kò sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ìhun orúkọ àbíkú oníyìsódì tí à ń ṣe àtupalẹ̀ rẹ̀. Àpilẹ̀kọ yìí lérò pé àgbéjáde tí a ṣe àfihàn rẹ̀ ní (8) kò rújú rárá, ó sì ṣe ìtẹ́wọ́gbà.

8. Béyìíòkú




[6] Wo Ilọri àti Oyebade (2012) fún àgbéjáde alápòólà ìyísódì méjì (double negation) fún àlàyé sí i.

Orúkọ àbíkú oníyìsódì odindi gbólóhùn/ìsọgbólóhùndorúkọ tí a lo ***Ajéìígbé*** gẹ́gẹ́ bí ọ̀sùwọ̀n fún àgbéjáde àwọn orúkọ bẹ́ẹ̀ tó kù ni àgbéjáde rẹ̀ lọ báyìí: atọ́ka àsìkò (AS) ***í*** yan APIṢ ***gbé*** gẹ́gẹ́ bí àfikún tí ó ṣe àgbéjáde àpólà àsìkò (APAS). Ní kété bẹ́ẹ̀ ni IY ***(k)ì*** tá mọ́ APAS láti ṣe àgbéjáde APIY, tí APIY sì ràn mọ́ APOR ***ajé*** (olùwà) ní ipò ASỌD, tí ó ṣe àgbéjáde ìhun orúkọ àbíkú oníyìsódì ìsọgbólóhùndorúkọ tí a ṣe àfihàn rẹ̀ ní (9). A kò gbé fọ́nrán ìhun kan láti ipò síńtáàsì rẹ̀ lọ sí ibòmíràn nínú irú àgbéjáde báyìí. Àwọn wúnrẹ̀n ọ̀rọ̀ kàn ta mọ́ ara wọn ni láti ṣe àgbéjáde ìhun orúkọ àbíkú náà.

9. Ajéìígbé




## 6. Ìgúnlẹ̀

Pépà yìí ti ṣàfihàn ìyísódì tó ń wáyé nínú àwọn orúkọ àbíkú Yorùbá. Ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìhun mẹ́ta ni ìyísódì yìí ní nínú orúkọ àbíkú Yorùbá: alápòólà ìṣe, aláwẹ́ gbólóhùn, àti olódindi gbólóhùn. Àpilẹ̀kọ yìí fi hàn pé àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì náà tẹ̀lé ìlànà tó ń ṣe àgbeyọ ìhun gbólóhùn kan nínú èdè ọmọnìyàn (àpólà → awẹ́-gbólóhùn → gbólóhùn). Èyí fidí èrò Obieng (2001:114) múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Ogunwale (2016:53) pé ìhun mẹ́ta ni púpọ̀ nínú orúkọ ilẹ̀ adúláwọ̀ (Yorùbá fún àpẹẹrẹ) máa ń tẹ̀lé. Pépà yìí kò ṣàìwí àwíjáre pé abala méjì ni ó wà nínú orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́ gbólóhùn. Abala àkọ́kọ́ ni òbí fi ń fún ọmọ ní orúkọ, nígbà tí abala kejì jẹ́ mọ̀-ọ́n-nú fún òbí àti àwùjọ. Iṣẹ́ yìí tún jírọ̀rò lórí àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì tí wúnrẹ̀n ìyísódì wọn kò fojú hàn nínú ìhun òke àyàfi nínú ìhun ìpìlẹ̀ alálàyé ajẹmọ́-sèmáńtíìkì. Lẹ́yìn náà ni àpilẹ̀kọ yìí ṣe àgbéjáde ìhun àwọn orúkọ àbíkú oníyìsódì Yorùbá náà nínú èyí tí a dábàá APIY1 àti APIY2 fún àgbéjáde orúkọ àbíkú oníyìsódì aláwẹ́ gbólóhùn àti èrèdí tí ó fi rí bẹ́ẹ̀.

## Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí


Adeoye, C. L. (1969). *Orukọ Yorùbá.* Caxton Press.

Adeoye, J. A. (2018). The Structure of Negation in Úwù. *Kansas Working Papers in Linguistics,* 39, 40-56.

Adebiyi, A. (2005). *Iran Yorùbá.* Milaax Compumagik Ventures.

Adewọle, L. O. (1999). Negation in Ifẹ̀: A Yorùbá Dialect. *Journal of Asian and African Studies,* 58, 397-403.

Awobuluyi, O. (1978). *Essentials of Yorùbá Grammar.* Oxford University Press, Ibadan.

Ajiboye, O. (2016). *The Syntax and Semantics of Yorùbá Nominal Expressions*. M & J Grand Orbit.

Ajiboye, O. (2024). *New Horizons in Yorùbá Grammar*. Kingdom Arts Publishing.

Bamgboṣe, A. (1967). *A Short Yorùbá Grammar.* Heinemann Educational Books, Ibadan.

Bamgboṣe, A. (1990). *Fọnọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. University Press Plc.

Banjọ, L. A. (1974). Sentence Negation in Yorùbá. *Studies in African Linguistics,* 5, 35-47.

Baker, M. C. (2003). *Lexical Categories: Verbs, Nouns, and Adjectives*. Cambridge University Press.

Chomsky, N. (1957). *Syntactic Structures.* S-Gravenhage (The Hauge), Mouton & Co.

Chomsky, N. (1995). *Minimalist Program.* MIT Press, Cambridge, Mass.

Chomsky, N. (1998). The Minimalist Enquiries: The Framework. MIT. *Occasional Papers in Linguistics*, *15*, 30-75.

Chomsky, N. (2002). *On Nature and Language.* Cambridge University Press, Cambridge.

Collins, C. (2011). Introduction to Minimalist Syntax. Lecture Notes, New York University.

Ẹlẹshin, B. (2015). Ìhun àti Ìtumọ̀ Orúkọ Asẹ̀dá Yorùbá Nípa Àfọ̀mọ́. *Láàńgbàsà, 19,* 21-36.

Erteschik-Shir, N. (2007). *Information Structure: The Syntax-Discourse Interface*. Oxford University Press, New York.

Fabunmi, F. A. (2013). Negation in Sixteen Yorùbá Dialects. *Open Journal of Modern Linguistics, 3*(1), 1-8.

Haegeman, L. M. V. (1991). *Introduction to Government and Binding Theory*. Oxford: Blackwell.

Haegeman, L. M. V. (1995). *The Syntax of Negation.* Cambridge University Press.

Obieng, S. G. (2001). *On Ethnopragmatic and Morphological Study of Personal Names in Akan Societies*. Lincom Studies in Anthropology, Muechen, Germany.

Ogunbọwale, P. O. (1970). *The Essential of the Yorùbá Language.* London University Press.

Ogunwale, A. (2016). *Naming in Yorùbá: A Sociolinguistic Exposition.* Obafemi Awolowo University Press.

Oke, D. O. (1982). *On the Use of Verbal Negators in Yorùbá*. In A. Afolayan (Ed.) Yorùbá Language and Literature, Ile-Ife University Press.

Oyebanjọ, ati ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ (2009). *Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá Titun, Ìwé Kejì*. University Press, Ibadan.

Ilọri, J. F. (2010). *Nominal Constructions in Igálà and Yorùbá.* PhD Thesis, Adekunle Ajasin University.

Ilọri, J. F. & Oyebade, F. O. (2012). Negation in Igálà. *Entrepalavras: Revista de Linguistica do Departamento de Letras Vernáculas da UFC,* 2(1), 25-40.

Ilọri, J. F. (2015). Ìhun Àwọn Ìsọ Ẹlẹ́rùn-ún *Ní* Yorùbá. *Láàńgbàsà, 19,*125 - 145.

Kayne, R. S. (1994). *The Antisymmetry of Syntax*. MIT, Cambridge University Press.

Pollock, J. (1989). Verb Movement, Universal Grammar, and the Structure of IP. *Linguistic Inquiry*, 20(3), 365-426.

Oye Taiwo (2016). The Syntax of Sluicing in Yorùbá. *Journal of the Linguistic Association of Nigeria, 1.*

De Vries, G. (1992). *On Coordination and Ellipsis*. Doctoral Thesis, Katholiek University, Brabant.